WEEKS 22&23
Kongi WK 22
8 14 36
Wk 23
3 17 37
Asiko BK WK 22
7 10 32 43
Wk 23
4 19 22 32
Wk 22
Ross Wk 22 16 & 50
WK 23
40& 45

# Imọlẹ Owurọ

ESIN ORO WA: IMOLE DE OKUNKUN PARADA!

SAMCO OF NIGERIA
WK 21
NAP 11 21 51
Perm 3 11 21 29 51
My Address ?
Not nessesary,
Always meet me in
Imole Owuro
Every Saturday

5 29 48

Independent Paper Vol. XVI — O 828, SATURDAY DECEMBER 31 – FRIDAY JANUARY 6, 1978 BK. KOBO MEWA

# ỌRỌ EGBE OGBONI GBE WOLI DE ILE EJỌ

ỌRỌ iwaasu l'ori ẹgbẹ okunkun ti o fa ẹsun idalur ati didigbolu Ọga Ọlọpa, ti gbe Woli Ijọ Sẹlẹẹṣia kan de ile ẹjọ Chief Magistrate ilu Ado-Ekiti ni Ipinlẹ Ondo.

Woli naa, unday Amuleya ti Opopo Ore-reowu ni Ado-Ekiti, ẹni ti o sọ pe, Ẹmi M·mọ l'o ran oun lati maa waasu lodi si iwa buburu gbogbo ati ẹgbẹ okunkun bi Ogboni ati bẹẹbẹẹ lo, ni awọn Ọlọpa fi ẹsun kan nile ẹjọ giga naa pe, o digbolu Ọga Ọlọpa agbegbe Ado Ekiti, Ọgbẹni Superintendent J. O. Akpojuyobi, o si da ilu ru.

Ọkunrin Woli naa Suuday Amuleya, sọ fun ile ẹjọ giga naa pe oun ko jẹbi rara. O ni nigbati oun nwaasu lodi si iwa buburu gbogbo ati ti Ẹgbẹ okunkun nilu Ado-Ekiti ni ọjọ ti a nwi yi, ni awọn Ọlọpa kan deede ki oun mọlẹ, wọn lu oun, wọn si mu oun lọ.

Sunday sọ pe, bayi ni awọn Ọlọpa ṣe mu oun lọ si ago wọn ti wọn si sọ pe, ori oun ti yi, bẹẹ ni arun ọpọlọ ko ṣe oun ni t'oun.

Sunday sọ pe nitootọ ni oun naa digbolu Ọga Ọlọpa ti wọn wi, ṣugbọn oun ko mọ pe Ọlọpa ni i ṣe. O ni lati ọjọ ti a nwi yi ni awọn Ọlọpa ti ju oun si itimọle.

Ninu ọro rẹ, Adajọ ile ẹjọ naa, Ọgbẹni J. K. Adeiribigbe sọ fun ọkunrin naa pe, [illegible] nikan ko le ba Ẹgbẹ okunkun [illegible] ajayege papa [illegible] o ṣe jẹ pe Ijọba ko pilẹ pa Ẹgbẹ naa rẹ ni ilẹ wa bikoṣe pe, ohun ti Ijọba ṣe ni pe, o paṣẹ pe ki awọn oṣiṣẹ Ijọba ti o ba nṣe ẹgbẹ naa tara kuro nibẹ ki iṣẹ ma baa bọ mọ wọn lọwọ.

Nigbanaa ni Adajọ paṣẹ pe ki wọn mu ọkunrin naa pada si itimọle titi di igba ti idajọ yio waye l'ori ẹjọ naa ṣugbọn o paṣẹ pe ki dokita maa bojuto alaafia rẹ ni itimọle naa.

## Aso 'Wonyosi' tun wolu!

Ọwọ awọn ọlọpa ilu Eko ti tẹ tọkunrintobinrin kan lori ọrọ siṣe fayawọ kọ ọpọlọpọ ẹru aṣọ Wọnyọsi wọlu pẹlu oniruuru aṣọ leesi ti Ijọba Ologun Apapọ ti fi ofin de. Bakannaa ni ọwọ awọn ọlọpa tẹ ọpọlọpọ apoti ọti lile pẹlu.

Irohin sọ pe gbogbo ẹru fayawọ ti wọn gba naa to ọlọkẹ marun Naira(₦100,000).

Gẹgẹ bi irohin loju ọna titun (express road) to wọ ọna ilu Agbadarigi (Badagry) ni ọwọ ti tẹ mọto akẹru nla kan ti aṣọ wọnyọsi naa kun inu rẹ bamu.

Wọn ni bi awọn Ọlọpa ti dubu mọto akẹru naa ni dẹreba ti o nwa a ba kanlugbo ni tirẹ ti o si lọ raurau, ṣugbọn ọwọ awọn Ọlọpa

(Woju Ewe Kẹjọ)

## Apprentices Wanted

LEARN to become a successful printer; learn on modern machine with modern technique.

Parents, don't waste the time of your fresh Primary Six & Modern III School leavers; send them to learn modern Printing, Machine operating and Book-binding from us. Apply personally today.

The Works Manager,
(Imole Owuro)
N4/496B Yemẹtu Aladorin,
Ibadan

## Ẹ ku Ọdun O!

ILE IṢẸ
ADETUNJI OMO AJE SOUND STUDIO
LO NKI YIN

LATI igba die sẹhin bayi ni Ile itaja ADETUNJI RECORDS ti bẹrẹ si i ta awo titun ti awọn gbajumo alare olokiki bii Apala, Wọrọ, Fuji ati Kewu ṣẹṣẹ ṣe fun igbadun lasiko ọdun titun ti a wa yi, ti awọn eniyan si ndu u ra witiwiti.

Pabambari are atata ni are ti awọn alare na ṣe sinu awo wọn na gẹgẹ bi awọn eniyan ti nra a paapaa ti jẹri si i, koṣemani ni; bi eniyan ba si fi eti gbọ are inu awo wọn naa, yio gba pẹ, otitọ ni.

Orukọ awọn gbajumọ alare ti wọn ṣẹṣẹ ṣe awo titun na pẹlu nọnba wọn ni wọnyi:

1. Ẹgbẹ Alare Atidade Kinniun Ọyọ ati are Wọrọ rẹ ti nonba rẹ jẹ 0LPS 0103
2. Amuda Oojere ati ẹgbẹ aṣare Apala rẹ ti wọn gbajumọ bi isana ẹlẹẹta ninu are apala asiko ni ilu Ibadan. Nonba awo rẹ jẹ 0LPS 0145.
3. Alhaji Kawu Aminu ati ẹgbẹ alare Faaji rẹ, ti nọnba rẹ jẹ 0LPS 0150.



OLORI Ẹgbẹ Atidade Kiniun Ọyọ.

Awọn awo mẹtẹẹta wonyi ni o dara fun faaji pẹlu orin agbọkọgbọn inu won. Irohin ko to afetigbọ ni.

Awo kẹrin ni ti Ọjọgbọn Onimọ Ijinlẹ nipa Islam Alhaji Ahmad Abdul AL-Adabiyy, eyi ti o fi sọrọ nipa Mẹka. Gbogbo Musulumi ni o yẹ ki o ni awo yi lọwọ, nitori ọrọ iyebiye ti o wa ninu rẹ ni yio ṣe gbogbo ẹni ti o ba ngbọ ọ ni anfani.

Ẹ beere eyi ti ẹ ba nfẹ ninu awo na ni ile-itaja rẹkoodu ti o wa ladugbo yin tabi lọdọ;

ADETUNJI STORES
2, Ibomọ Street,
Ita Agarawu
Phone 26813, Lagos.
*Sw6/431 Old Armel's Rd,
Telephone 21304,
Ogunpa, Ibadan.
* Adetunji House,
Sw3/61 Popoyemọja,
Ibadan.

# ATIORO OMO ATIALA

## Asinilona Oba (4)

MO tun gbe kiniyi de,
Omọ araye:
Gbogbo eniyan ilu
L'a nba wi
Ẹ wa gbọ Nasia.
Nasia miran kọ.
Eyi ti a nwi
Lori awọn Ọba ni,
Awọn Ọba iwoyi
Ti nṣi gbogbo ilu lọna.
Ẹ ma gbagbe o
Kii ṣe gbogbo Ọba
Ti nbẹ nilẹ wa
L'a nwi gbogbo
Bikoṣe pe Ọba
Ile Yoruba
Ti nṣi ilu lọna
L'a nba wi
Ninu Nasia.
Gbogbo Ọba ilu kọ o
Ẹyin janmaa.
Awọn Ọba ti a wi ni
Awọn Ọba kan
Ti wọn ko joye aborẹ
Ṣugbọn ti wọn sọ
Ara wọn di



Aborẹ f' Ooṣa!
Awọn Ọba to yo tan
T'o nkọ ilu
Lati maa bọriṣa kiri
Awọn Ọba
T'o gori itẹ tan
T'o wa d' iranṣẹ Eṣu
Awon ni nkesi ilu
Pe ki wọn jade wa
Lati waa foribalẹ
Fun Ooṣa baba wọn!
Awon naa a ṣaaju
Wọn a maa jojo iya;
Wọn i pọlọ lori,
Wọn mọwe daju,
Wọn laju,
Wọn si gbajumọ
Ṣugbon o ṣe ni laanu
Pe, pelu gbogbo
Imọ wọnyi,
Ooṣa ti ko le sọrọ,
Ti ko lagbara
Ani, igbagbọ eke
Ti awọn baba wọn ni
Nigba t'oju dudu,
Ni wọn tun nlepa!

O wa jẹ pe
Pelu ọlaju ati
Gbogbo imọ
Ti wọn ni,
Wọn ko tun ṣaaju
Awọn baba wọn lọ!
Igi tọmọ araye fẹwọ gbẹ
Ni wọn nwari fun!
Ṣigidi amọ ni
Wọn nforibalẹ fun!
Odo t'Ẹlẹda da
Pe, ka maa lo
Ka maa pọn mu,
L'ọmọ araye nbọ!
Wọn a kowo,
Wọn a kobi,
Wọn a se onjẹ,
Atọna Atijoye,
Wọn a maa jijo iya
Wọn a maa bọ
Ẹja ti nbẹ nilẹ odo
Ṣebi baba Eebo
Ti bọ oorun
Ati oṣupa ri
Nigba laelae?
Ṣugbọn nigba to ya
Ti oju wọn la,
Awọn ọmọ wọn pa a ti,
Wọn rii pe asan ni.
Ṣe bi nigbayi ni
Iran Eebo to goke
Ti wọn dalagbara!
Ọlọrun si ṣetan
O ran Eebo wa si
Ilẹ wa gbogbo,
Ekọ iwe bẹrẹ, ọlaju bẹrẹ,
Igbagbọ eke
Ninu igi bibọ
Ninu ooṣa bibọ
Gbogbo rẹ ndopin
Ilọsiwaju nde
Ko si ifinirubọ
Ko si ihalẹ Abọriṣa
Ko si iyọlenu Oniṣango
Bẹe l'gbe Oloro
Ẹgbẹ Oniṣanpọnna
Bẹẹ l' Ẹgbẹ
Alawo Ọpa
Ko lee dẹru ba ni,
Ẹsin ibọriṣa
Ati gbogbo iwọnyi
O si ti ndi ohun itan.
Bayi lọrọ ri o
Ẹyin ara wa,
Bayi lọrọ ri
Ni ilẹ Yoruba daka.
Ṣugbọn, ko tii pẹ ju
Ọdun marun bayi o
T' awọn Ọba kan yari
Ni ile Kaarọ Oo iire
Ti wọn d'aloreOriṣa.
Ti wọn d'abọriṣa kalẹ.
Wọn nda atọwọda
Ọdun Ooṣa silẹ
Ninu ilu wọn.
Won nkesi ara ilu
Pe ki wọn wa
K'awọn dijọ bọ Ooṣa!
Redio nke,
Iwerohin nke,
Wọn nke pe,
K'ara ilu wale pata
Kawọn dijọ lọ sojubọ;
Wọn a ni,
Bibọ Ooṣa wọnyi

Ni yio jẹ ki
Ilu tuba tuṣẹ!
Ẹyin eniyan wa!
Ọrọ lẹ ngbọ yi
Bi ng bo parọ,
Ẹ maa ja mi o;
Bi ẹ ba wo
Ọpọ ilu Yoruba loni,
Nṣe lọba wọn
Ti wa di Ọba Olooṣa.
Wọn nṣi ilu lọna,
Wọn ntan ilu sinu
Ohun ti yio ba ilu jẹ?
Wọn ndari
Eni ti a fi si
A be itọju wọn sọna iparun!
Wọn ko bẹru Odumare
To fi wọn sori ipo
Pe yio beere
Iṣẹ itiju wọn
Niwaju Onibode
Lọna ọrun!
Wọn ko ranti
Pe, ewu nla
Lo nbẹ lori
Ẹni a fi tekoko ilu,
Nitori, ẹṣẹ nla lo jẹ
Bo ba ṣi ilu lọna.
O yẹ ki
Onikaluku ranti
Pe, ijiya tara ilu
Ko nii to
T'eni to ṣi ilu lọna
Niwaju Olodumare
Ọba Ọrun!
A o maa tẹsiwaju
Bo ba dosẹ to nbọ.

ỌLỌLA ATIORO

## NI IRANTI

BABA WA ỌWỌN



SAMUEL ADIGUN MAGBAGBEỌLA

(Baba Oyinbo Ọmọ Oyewusi Oniyikaye):
A ki i ni'nu 're k'a ma ku l'aye.

Adigun Oki! Ba a n'iya la a hun, ba a hun s'eniẹleni, a gba ni n'igi l'ẹnu. Gbangboye! Ogun ewe ni mo pe, igba lo jẹ mi l'oju ẹlọ. Ọmọ Oyetunde, ọmọ ewe ile.
Adigun Oki!
K'a to r'erin o d'igbo.
K'a to r'efon o d'ọdan.
Ng o ṣe bi iya ko le jọ iya
Ng o ṣe bii baba ko le jọ baba
Adigun Oki, aye l'ọja ọrun n'ile.
Ojoojumọ ni awa nranti rẹ lati ọdun meji ti o ti fi wa silẹ lọ ile ayeraye. Awa dupẹ pe Ọlọrun ko fi wa silẹ. Adigun Oki Sunre o! Sunre!!

Isaac I. Magbagbeọla
(Fun Gbogbo Ẹbi)

## Oba Fese Fee

OLOYE Adoyi Edubo, ẹni ti awọn ara ilu fẹ fi jẹ Alegwu ti Adoka ni Ipinlẹ Benue, ni a gbọ wipe o fi ere gee nigba ti awọn janduku kan digbolu wọn nibi ti awọn afọbajẹ ti fẹ jawe oye le ọba na lori.

Iṣẹlẹ na ṣẹlẹ ni ojubọ kan ni ilu naa ni asiko ti ifinijọba bẹrẹ. Bi awọn afọbajẹ ti bẹrẹ si i ṣe ojuṣe wọn, ni awọn janduku eniayan naa ba jalu wọn ti wọn si ba aṣeyẹ ọjọ na jẹ.

Irohin ti o de etigbo wa sọ pe Ọba naa ati awọn ẹmẹwa rẹ ati awọn ibatan rẹ ti sa asala lọ si ilu kan ta npe ni Okpufalọ ti ko ju ibuso mẹẹdogun si Adoka, eyiti o wa ni agbegbe Oturkpo ni Ipinlẹ Benue ni Oke-Ọya.

Gẹgẹ bi a ti gbọ, awọn janduku naa nfi ihonu wọn si yiyan ti wọn yan Ọba na han ni.

Woju Ewe Kẹjọ

# ABA OFIN ETO ISELU NIGERIA (20)

ẸYIN enlyan wa, a o bẹrẹ ọrọ wa t'oni labẹ "KI ENIYAN TO LE WỌLE IGBIMỌ AṢOFIN ATI IYEJU ẸNI TO LẸTỌ LATI BA WỌN ṢE IPADE". Ki a ma wulẹ ṣe ifaara lori eyi mọ, ẹ maa ka ọrọ naa lọ bayi:

63– Nitori ohun ti a kọ ni esẹ 64 Ofin yi,

(a) Ẹnikẹni lo ni ẹtọ aṣẹ pe ki a dibo yan an gẹgẹ bi ọmọ ile Igbimọ Aṣofin Agba (Senator), bi ẹni naa ba ti jẹ ọmọ bibi Naijira ti o si ti to ẹni ọdun marun—dinlogoji.

(b) Ẹnikẹni lo ni ẹtọ aṣẹ pe ki a dibo yan an gẹgẹ bi ọmọ Ile Igbimọ Aṣofin yoku, bi ẹni naa ba sa ti jẹ ọmọ bibi Naijiria ti o si to ẹni ọdun mọkanlelogun.

64- Iru awon wọnyi ko ni i lẹtọ si aṣẹ ki a dibo yan wọn wọle sinu eyikeyi ile Igbimọ Aṣofin.

(a) Bi iru eni bẹẹ ba ti funra rẹ finnufindọ di ọmọbibi Orilẹ-ede miran yato si Naijiria tabi o tilẹ ti sọ gbangba pe ti iru Orilẹ-ede bẹẹ ni oun (aya tun fi lona miran ti Ofin ile Igbimo Aṣofin ba so.)

(b) Bi a ba ti gba pe asinwin tabi ẹni ti ori re ko pe ni onitohun, labe Ofin yowu ti o wa nibi yowu ni igun mẹrẹẹrin Naijiria.

(c) Bi ile ẹjọ olofin kan ni Naijiria ba ti da oluwa rẹ l'ẹjọ iku tabi ti o ti gba idajọ ẹbi ọran aiṣododo (orukọ yowu ki a pe iru aiṣododo bẹẹ) ti idajọ ẹwọn rẹ si ju oṣu mefa lọ. Ṣugbọn ṣa, Igbimọ Aṣofin Apapọ le lana silẹ fun ẹni naa ti ori rẹ ko pe, ẹni ti o ti gba idajọ ẹwọn ti o jẹmọ iku, tabi odolugbese, lati fi le pejọ kotẹ—milọrun bi o ti ṣe yẹ labẹ ofin eyi—keyi ti o ba mulẹ nibikibi ni Naijjria (Ipinnu lori kotẹ—milọrun bee ko ni i ti i mura fun ti esẹ ofin yi, titi awọn Alaṣẹ yio fi paṣẹ.)

(d) B'o ba jẹ pe, l'ẹnu ọdun mẹẹdogun ki o to di ọjọ idibo-wọle Igimọ Aṣofin naa ni onitọhun ti gba idajọ ẹwọn nitori iwa ti o jẹmọ aiṣododo, tabi ti o jẹbi riru ofin ti a fi gbe iṣiṣẹ eni lododo kalẹ (code of conduct.)

(e) Bi onitọhun ba jẹ odolẹgbeku onigbese ti ko ti i bọ ninu ajaga gbese naa, ti o ba jẹ pe ofin eyikeyi nibikibi ni Naijiria lo mu oluwa rẹ ni odolugbese bẹẹ.

(f) Bi o ba jẹ pe oṣiṣẹ Ijọba Apapọ, ti Ipinlẹ eyikeyi, ti Ijọba Ibile, ti Ajọ ile iṣẹ okowo Ijọba ni onitọhun, tabi pe o jẹ oṣiṣẹ ile Igbimọ Aṣofin kan ile ẹjọ, oloogun.

Tabi pe oluwa rẹ ti-jẹ oṣiṣẹ bẹẹ ni aarin oṣu merin ki ibo didi naa to bẹrẹ: Bi eni t'o ba jẹ oṣiṣẹ ti Ajọ ile iṣẹ oko-wo Ijọba, ti Apapọ tabi ti Ipinle, tabi ti Igbimọ Ijọpa Ibilẹ, ba fa ara rẹ kalẹ ni idibo, ti wọn si dibo yan a n wọle, sile Igbimo Aṣofin eyikeyi, a jẹ pe iṣẹ rẹ ti duro nile iṣẹ [illegible]

65–(1) Alakoso Ijọba Apapọ le wa ni ipade ẹyikeyi Igbimo Aṣofin Apapọ ki o si ba wọn jiroro nibẹ, bi o ti lẹ jẹ pe ki iṣe ọmọ ile Igbimọ Aṣofin bẹẹ.

65–(2) Alaṣẹ Ijọba Ipinlẹ kan le wa ni ipade ile Igbimọ Aṣofin Ipinlẹ naa ki o si ba wọn jiroro nibẹ, bi o tilẹ jẹ pe ki iṣe ọmọ ile Igbimọ Aṣofin bẹẹ.

65–(3) Ko si ohunkohun ninu abala esẹ ofin oke yi ti a le sọ pe o fun ẹnikẹni ti ki iṣe ọmọ ile Igbimọ Aṣofin ni ẹtọ lati ba won dibo nibẹ tabi ba wọn dibo pelu ninu ipade Igbimọ Alabẹṣekele ibẹ.

66–(1) Ọmọ Ile Igbimọ Aṣofin kan yio fi ipo rẹ silẹ ninu ile naa;

(a) Bi o ba jẹ pe o tun di ọmọ ile Igbimọ Aṣofin miran yatọ.

(b) Bi ohun miran ba ṣẹlẹ pe, bi ko ba jẹ ọmọ ile Igbimọ Aṣofin ti o wa yi, yio fa ki a fagile ẹtọ rẹ ki a le dibo fun un wọle.

(c) Bi ko ba jẹ ọmọ bibi Naijiria mọ. Bi o ba di Olori ilẹ wa, tabi Igbimọ wa, tabi Igbakeji Olori ilẹ wa, tabi Gomina, Ijọba Gomina, Alakoso Ijọba Apapọ tabi Alaṣẹ Ijọba Ipinlẹ kan.

(e) Bi o ba di ọmọ inu Igbimọ kan tabi Ajọ ile iṣẹ miran ti ofin yi tabi ofin

(Woju Ewe Keje)

## Lati Owo Lawuyi Ogunniran



AWORAN oke yi nṣe afihan ara awon oloṣa ti won ti yinbon pa ni ile Naijiria leyin ti ile ejo ti da won lebi iku. Labe Ofin yi gege bi e ti ka a, enikeni ti o ba ti gba idajo iku fun jijebi esun kan labe ofin ko leto lati dibo lo si ile Igbimo Aṣofin.

# Akede ọna Iye

# Wa sinu Imole Jesu Lati Odun yi lo



WOLI S.I. OWOẸYẸ
Oniwaasu Naa.

"NITORI Ọlọrun fe araye to bẹẹ gẹẹ ti o fi ọmọ bibi rẹ kanṣoṣo fun ni ki ẹnikẹni ti o ba gba a gbọ ma ba a ṣegbe. Ṣugbọn ki o le ni iye ainipẹkun. Nitori Ọlọrun ko ran ọmọ rẹ wa si aye lati da araye l'ẹjọ, sugbọn ki a le ti ipaṣe Rẹ gba araye la. Ẹni ti o ba gba A gbọ, a ko ni i da a l'ẹjọ, ṣugbọn a ti da ẹni ti ko gbaa gbọ l'ẹjọ na, nitori ko gba orukọ ọmọ bibi kanṣoṣo ti Ọlọrun gbọ. Eyi ni idajọ naa pe, Imọlẹ wa si aye, awọn eniyan si fẹ okunkun ju Imọle lo nitori iṣẹ wọn buru" Johanu 3: 16-19.

Ogo ni fun Jesu Kristi ti o mu wa la ọdun yi ja l'ayọ ati alaafia. Ọpẹ lo yẹ Oluwa Ọlọrun Olodumare.

Ki eniyan to jade lati inu iya rẹ, oriṣiriṣi iṣoro ati inira ni iya rẹ yio ti ri ninu oyun, titi di ọjọ ti yio bimọ. Bẹẹ gẹgẹ ni ẹni ti o ba la ọdun kọja bọ sinu ọdun titun ko ṣai ni i ti ba oniruuru iṣoro pade ni ọdun ti o koja.

Ọlọrun ni o mu ki a le la gbogbo iṣoro naa kọja ti a fi bọ si ọdun titun. Ọlọrun l'o daabobo wa lati ibẹrẹ ọdun eṣi wa ti ko si jẹ ki a ṣegbe. A wa lai lewu, a wa lai ri ebi, a wa lai ri ogun ati rogbodiyan, ọwọ wa si nte ohun rere. Nje iwọnyi ko to ọpẹ fun wa l'ọdọ Ọlọrun. Ẹni ti o ṣe eyi fun wa nipasẹ Jesu Kristi?

Jẹ ki o ye ọ nitorina iwọ ọmọ eniyan pe nipa oore-ọfẹ Ọlọrun, eyi ti a fi fun wa nipasẹ Jesu Kristi ni a fi le maa ri iru oore, aabo ati ibikun bayi ati ju bẹẹ lọ pẹlu. Ninu Jesu yi pẹlu ni Ọlọrun si ti lana iye fun olukuluku ọmọ eniyan.

Nitorinaa, bi iwọ ko ba tii mọ tẹlẹ, tete lọ mọ loni yi pe, Jesu Kristi nikanṣoṣo ni Ọna Iye, Oun nikan ni Ọna Igbala-nipa rẹ nikanṣoṣo ni eniyan si le ri Ọlọrun. Bi ẹnikẹni ba nsọ fun ọ pe ọna miran wa ti o le gba, maṣe gba a gbọ nitoripe Jesu Kristi nikan ni Ọna naa.

Iwọ omo eniyan, gba eyi ti mo nsọ ni ọtun fun ọ yi gbo sinu ọkan re nitoripe ninu okunkun ni gbogbo awon ti ko gba Jesu gbo tọkantọkan wa.

Ranti pe, ọdun ogbologbo yi ti pari, titun si wọle de. Eṣu ẹni ibi nni ti tun ran awon ọmọ ogun rẹ jade ninu

Herodu Ọba ko gba Jesu Krist gbọ o si parun ati ọpọ eniyan l'ode oni pẹlu ti wọn ti parun.

Nitorinaa iwọ ọmọ eniyan, Jesu Kristi ni ki o gbagbọ, Oun ni ki o si gbẹkẹle ninu ohun gbogbo nitoripe Oun ni ẹni ti o tọ mi lẹyin ki yio rin ninu okunkun sugbọn yio ni. Imọlẹ Iye Johanu 8, 12.

ADURA

Jesu, mu mi lati gba ọ gbọ ki nma baa ṣegbe Jẹ ki nmaa gbe ninu Imọlẹ Rẹ lati ibẹrẹ ọdun

## Lati Owo Woli S. I. Owoeye

iwa okunkun won sinu aye, enikẹni ti o ba si gba Jesu Kristi gbo ni Olugbala ti o si jẹwọ Re ni Ọmọ Ọlọrun, ni yio le riran ninu okunkun naa, a ko si ni da oluwa rẹ lẹjọ.

Mo tun ntẹ ẹ mọ ọ leti iwọ ọmọ eniyan pe ẹnikẹni ninu aye yi, iru esin yowu ki oluwa rẹ lẹ maa sin, koda bi o pe pe ara re ni Onigbagbo, bi oluwa re ko ba gba pe Jesu Kristi ni Olugbala araye, ti ko si pa Ofin Rẹ mọ, iru ẹni bẹẹ ntan ara rẹ je ni ọrun apaadi l'o fi nṣere nitori a o daa lẹjọ aigba Jesu Kristi gbọ.

Ṣugbọn bayi, a ti da awọn kan l'ejo na. Ani, awọn ti eṣu nlo lati kiri okunkun laye, yala tori ki wọn baa le lowo tabi ki wọn baa le l'oruko. Melo la o ka ninu iru wọn ti orukọ wọn naa ti bajẹ kanlẹ nipa pe, eṣu l'o fun wọn l'orukọ naa?

Ẹ jẹ ki ẹni ti o ba nfi ilana eṣu wa orukọ ranti pe, nitootọ ni eṣu yio fun un ni orukọ ti yio idi itiju fun oun naa ni gbẹhin.

Imọlẹ aye. Bi iwọ ba si nrin ninu Imọlẹ Rẹ, rere ni gbogbo orọ rẹ yio maa jasi, adura rẹ gbọgbo ko si nii inidena.

Gbogbo ẹni ti ko ba gba Jesu gbọ wa ninu okunkun aye; ẹnikẹni ko si le wa ninu okunkun ki ọrọ rẹ jasi rere.

Nitorinaa, odun ogbologbo yi nkọja lọ, omiran si ti wọle de, Jesu npe ọ bayi pe ki o pada kuro lẹyin eṣu. Jesu Kristi, ẹni ti o setan lati gba ẹlẹṣẹ la, nke si ọ pe ki o tara wa ki o baa le gba ẹmi rẹ la nisinsinyi nitori bọya ọla le pẹju. Jesu nsọ fun ọ nihin pe, "Emi ni Imọlẹ aye,

1978 yi lọ ati titi laelae Aamin.

ANFANI FUN Ọ

Bi o ba ni iṣorokiṣoro ninu aye rẹ, eyi ti eṣu tabi ẹṣẹ, tabi aigbagbọ mu ba ọ, kọwe si mi nitoripe Jesu Kristi nduro de ọ lati ba ọ sọ oke iṣoro rẹ di pẹtẹlẹ gẹgẹ bi Jesu ti wi ninu Matteu 7:7; Matteu 10: 8.

Ṣugbọn bi o ba nkọ iwe si mi, maa fi envelope ti o kọ adirẹsi rẹ si ketekete pẹlu stamp 5k sinu iwe naa ṣọwọ si:
Woli S. I. Owoẹyẹ
41, Ibikunle Avenue,
Bodija-Ibadan.

Ki ṣe pe ki o tọ mi wa. Iwe ni ki o kọ si mi.


## Kalenda Igbaelode

EYI ni lati sọ fun gbogbo eniyan paapaa eyin onibara wa pe, Kalẹnda Alufaa Yisa Igbaẹlode ti 1978-Ti nọnba pupa nka Oṣupa ti Nọnba dudu nka oṣu Oyinbo, ti jade bayi fun tita.

30k ni ẹyokan, Dọsinni iẹ ₦2.40. Tete lọ ra tirẹ l'ọdọ awọn ti o nta Tira kaakiri tabi beere lọdọ:

(1) Alhaji Mustafa,
N1/315 Ayẹye Market,
(Lẹhin Ile Idalẹnu)
Ibadan.

(2) Alufaa Y. Igbaẹlode,
N2/394A Odoye
Adeọyọ Road,
P. O. Box 3365,
Mapo, Ibadan.

Kiyesi i pe, Igbaẹlode Kalẹnda ni o ra Nitoripe ayederu rẹ pọ l'ode.



## IWE ỌRỌ ỌLỌRUN

Fun anfani ẹnyin ti o ṣoro fun lati ri iwe mi yi ra ni ọkookan, mo ti ṣeto lati maa fi apapọ iwe na ṣọwọ si nyin ni Naira kan pere. (₦1.00)

1. ADURA AIYERAIYE
2. IBANIWI OLUWA
3. KINI ILE AIYE ṢE BAJẸ ?
4. Ẹ JOWO ARA YIN FUN OLUWA

Bi o ba ti fi Postal Order ₦1.00 ṣọwọ si mi, ng o fi apapọ iwe na ṣọwọ si ọ lagbara Oluwa. Fi owo ranṣẹ si:
Woli S. I. Owoẹye
41, Ibikunle Avenue,
Bodija- Ibadan.

# Sora ki Haji re ma baa baje

IWAASU mi yi duro lori akọle ti a kọ soke yi. Ikilọ ni ọrọ naa pe, ki o ṣọra ki Haji rẹ ma baa ṣe baje. Ẹnikẹni ti o ba nhuwa ibajẹ lẹyin ti o ti de lati Haji, nṣe ni o nba Haji rẹ je.

Ọrọ Ọlọrun sọ ninu Alukuraani Mimọ Suratu 22 aya 31 pe,"Ni ti wiwa ni dede fun Ọlọrun ni aiko da nkankan pọ mọ Ọlọrun (nipaHaji yin). Ẹnikẹni ti o ba ṣe idapọ nnkan miran da bi ẹni ti o ja lori oke giga ti ẹyẹ ṣi gbe e lọ tabi ti atẹgun gbe e lọ sibi ti o jinna ninu ọgbun".

Nitorinaa ni mo ṣe nke si ọ lati daabo bo Haji rẹ. Iwọ Alhaji ati Alhaja ni mo nba wi. Tete jawọ ninu gbogbo ilana ti ko ba ofin Islam mu nitori ilana naa ni o nba Haji jẹ.

Ara iwa buburu naa ni, ki Alhaji tabi Alhaja ti Mẹka de tan, ki o wa lọ joko sile ki o si maa sọ pe lilọ si Jimọ oun ko ti i to nitoripe wọn ko ti pari aṣọ ti oun fẹ fi ṣe e.

Iru iwa yi ko ba ilana Islam mu-ilana eṣu ni. O ko nilati da Jimọ duro rara. Bi o ṣe pe ọjọ Jimọ ni o de, ẹtọ rẹ ni ki o lọ ki Jimọ.

Nitorinaa, daabo bo Haji rẹ daadaa nipa ṣiṣọra pẹlu awọn iwa ti o le ba Haji jẹ. Ẹnikẹni ti o ba daabo bo ẹsin nipa iwa rere, yio gba laada ẹni ti o daabo bo gbogbe aye. Ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba hu iwa buburu ti o fi ko leebu ba orukọ Islam, Oluwa yio je iru ẹni bẹẹ niya iwa ibajẹ ti o hu o.

Ojiṣẹ ola Molamed (S. A. W. S) sọ pe, Ẹnikẹni ti o ba ṣe Haji ti ko hu iwa ibaje, ti ko si ru ofin, a ti wẹ ẹ mọ kuro ninu ẹṣẹ rẹ o wa da bi ọmọ titun ti ko ni ẹṣẹ l'ọrun.

Jọwọ o, Alhaji ati Alhaja: ma ṣe fi alu jijo kun Haji rẹ. Maa daabo bo Haji rẹ nipa tilẹle ikilọ ti a ṣe fun ọ yi.

Ki Oluwa ma ba Haji yin jẹ o.

**Lati Owo Alhaji M. Aliyu**

## Ra Iwe Igbaelode

1. Iwe gbogbo Agbo Ọmọde ati Agba 20k
2. Kurani ọgọta esu ni ede Yoruba ₦10 Esu marun (₦1)
3. Yasin ni Yoruba ati Isawaka 50k
4. Zabura ati Itumọ (₦1)
5. Zabura Yoruba (₦1)
6. Iwe Aiye Akamara (₦1)
7. Iwe Eniaṣoro (₦1 Adedẹwẹ (50k)
8. Iwosan Ajẹbidan Ogun enia dudu (₦6); Kekere (75k)
9. Iwe ala nl nla (₦3)
10. Kekere (50k)
11. Iwe Oogun iwosan (₦2.50) Kekere (75k)
12. Itan Anabi ati Yisa (₦1)
13. English Hausa Yoruba & Ibo Registered No. 410 (50k)

FI OWO ATI STAMP (5k) RANṢẸ SI

(1) Alufa Yisa Igbaẹlode, N2/394a, Odo-Iye, Adeọyọ Road, P.O Box 3365, Mapo Ibadan.

(2) Alufa Igbaẹlode Mọṣalaṣi Idi Iṣin St, Isalẹ Koto, P. O. Box 17, Ilọrin.



IGBAẸLODE

## Won taja daran

AWỌN eniyan mẹrin kan ni ile ẹjọ ti nṣẹjọ awọn alajeju ere ju si apapọ ẹwọn oṣu mẹtalelogbọn tabi ki wọn san ẹgbẹsan Naira (₦1,800.00) owo itanran.

Awọn ọdaran naa ni Okure Ajah ti adugbo Kirikiri Eko, Afọlabi Oṣobanjọ ti o ngbe ni Yaba, Ọlakunle Tawo ti o ngbe ni Agege ati Alice Awonusi ti o ngbe ọna Ikorodu, Eko.

# Agbaagba Ifelodun nkowe

BAYI, awọn agbaagba ni iha Ijọba Ibilẹ Ifẹlodun ni agbegbe Ọsun ni Ipinlẹ Ọyọ ti nnifẹ si lilọ si ile iwe awọn agba.

Kansilọ fun eto ẹkọ fun Igbimọ Ijọba naa, Ọgbeni Isaac Adeọṣun l'o ṣipaya eyi nigba ti o nbaọpọlọpọ eniyan sọrọ ni ilu Obaagun laipẹ yi.

Nibẹ ni o ti sọ pelu pe ẹedegbeta agbaagba lo ti fi orukọ wọn silẹ bayi lati kẹkọ ni ile ẹkọ awọn agbaagba fun akoko ọdun titun ti o wọle yi.

Bakanna ni oṣiṣẹ amuludun kan fun agbegbe ibẹ, Ọgbeni Johnson Babarinde sọ pe awọn eniyan ilu Ọbaagun ti pinnu lati la titi ibusọ mẹrin lati fi so ilu naa pọ pẹlu Inisa nipa iṣẹ iranraẹnilọwọ.


**Hacco NaP 29**



*For all your Electronics*




*PATRONIZE:*

**AIYEDETISOLA COMMERCIAL ELECTRICAL STORES**

AN 27 & 41 I.M.G. Stalls P.M.B. 38, Agodi Gate, Ibadan.

# Ẹgbọ t'emi

## Kinni itumo Kiriyo?

OLOOTU,

OPO igba ni mo maa ngbọ ọ ti mo si maa nka a, ti awọn ẹlẹsin Musulumi maa npe awọn Onigbagbo ni "Kiriyo". Mo wadi bawo ni orukọ naa ṣe waye, ohun ti wọn sọ fun mi ni pe, awọn Onigbagbọ ti o fẹran lati maa bẹ ile ẹlẹgbẹ wọn wo, ti awọn onitọhun si maa nṣe wọn lalejo l'o fa a ti wọn fi maa npe wọn ni "Kiriyo" nitoripe wọn a maa jẹun yo nibi ti wọn ba ti nya ojule kiri. Nje otitọ ni eyi?.

Emi ni,
Iṣola Adegbindin,
Ogbomoṣọ

Akiyesi

Ọrẹ wa Iṣọla, nitootọ ni awa naa ti gbo iru itan ti o sọ yi ri ṣugbọn ko si ẹri ti o fi idi eyi mulẹ ninu iwadi. Ohun ti a kiyesi ni pe, idi ti wọn sọ naa ko fi otitọ han rara.

Ṣugbọn ninu iwadi tiwa, ẹya kan ti o wa ni Saro nigbati ẹsin Igbagbo debẹ ti a npe ni Creole, je iran ọmọwe akọkọ ni iha Iwọ-Oorun ile Afrika, awọn ni o si tan esin Igbagbọ de ilu Eko. Wọn tun je ọmọwe ọlaju ati oṣiṣẹ Ijọba. Orukọ ẹya naa- "Creole" ni awọn ara Eko sọ di "Kiriyo" nitori ai le pe Creole-(Krio) daadaa bii ti ẹni ti o ba gbọ ede Gẹẹsi Nihin ni awa gba pe "Kiriyo" ti wọn npe awọn Onigbagbọ ti jade, a si lero pe, iru awọn eniyan kan ti wọn maa nfi ọgbọn ori tumọ nnkan ni o sọ pe, nipa pe Onigbgbọ maa nyale ara wọn jẹun ni wọn fi npe wọn ni "Kiriyo".

— OLOOTU

## Ma sun igbo n'ina l'Ondo

IJỌBA Ipinlẹ Ondo ti ṣe ofin pe, enikẹni ko gbọdo sun igbo nina mọ jakejado Ipinlẹ naa.

Ọga Asọgbo fun Ipinle naa, Ogbẹni R. F. Ẹsan lo kede ọrọ naa nilu Akurẹ fun aye gbọ.

Ohun ti o mu ki ofin naa jade gẹgẹ bi Ogbẹni Ẹsan ti wi, ni pe, ọpọ agbẹ ni o ti di ẹdun arinle, ti ọpọ igi olowo iyebiye ati ohun ọgbin miran ti nmu owo wọle si ti jona ruuruu nitori sisun igbo nina.

O ni Ijọba Ipinlẹ naa nna ẹgbẹẹgbẹrun Naira sori didaabo bo awọn igbo Ipinlẹ naa. O wa rọ awọn agbẹ ati ọdẹ lati dẹkun sisun igbo nina paapaa ni awọn ibi ti o jẹ ọdan ni Ipinlẹ naa.

O wa kilọ pe ẹnikẹni ti ọwọ ba tẹ pe o nsun igbo nina yio f'ẹbọ jura.



ỌGAGUN I.D. IPEMẸ
Gomina Ondo

**20 24 25**

## Nasia Atioro fakiki

OLOOTU,

GBA mi l'aye lati sọrọ bii gbolohun melo kan lori oniruuru nasia ti Ọlọla Atioro ọmọ Atiala baba Atiẹlẹ naa nṣe sinu Imọlẹ Owuro.

Lai ṣe aniani, awọn nasia naa fakiki nitoripe ọgbọn ikilọ ati imọran atata kun inu rẹ.Ẹni ti Ọl·ruu ba nfe yio maa ronu lori gbogbo nasia naa ṣugbọn awọn ẹni ti eṣu nfẹ ko ni i ronu si i rara.

Iru awọn ẹni eṣu wọnyi ni nṣe ilẹ wa ni ibi, awọn naa si ni nasia Ọlọla Atiory nkilọ fun nigbagbogbo ti wọn ko tẹle e. Bi Ijọba ilẹ wa ti nṣe akitiyan to lati da awọn ẹni ibi naa lẹkun, wọn ko gb . Ọrọ Ọlọrun ninu Johanu Ori 3 ẹsẹ 19 l'o ṣe mọ wọn lara.

Nitorinaa, mo kan sara si Ọlọla Atioro fun nasia iye-biye rẹ, mo si rọ ọ lati tẹsiwaju.

Emi ni,
R.A. Ayanwale,
Ogbomoṣọ

**Nigeria New States Co.**

Jẹ atẹwe asiko. Bi o ba fẹ tẹ oniruuru iwe Kalẹnda, Almanak ati bẹẹbẹ lọ, Ile Iṣẹ wa wa ni :

18, Ọdunlami Street,
Phone 27017, Lagos.

**5 9 17**

**KEREO**

GBOGBO - ENIA!
fun

*Ipolowo oja ati Ikede,*
*Akiyesi ati Itufọ,*
*Iranti oku ati Ikede Ariya,*
*Ikilọ ati bẹbẹ lọ;*
*Tabi Almanak ati Kalẹnda tite.*

DARAPỌ PẸLU AWỌN OLOGBON ENIA TI ONSEE SI INU (IMỌLẸ OWURỌ) TI O GBAJUMỌ KARI AIYE. OWO TI A NGBA KOPO.SA KOWE TABI KI O WA RI:-

*Advertisement Manager:*

IMOLE OWURO
N4/496A YEMETU ALADORIN.
P.M.B. 5230, IBADAN.

# Elesin Ibile yio ko Yunifasiti

## — Fagbemi Ajanaku

ALAGA Egbe Elesin Ibile ile ajiria, Oloye Fagbemi Ajanaku ti iṣe Araba Eko ti ṣipaya pe Egbẹ oun yio kọ ile ẹkọ alakọbẹrẹ, ile ẹkọ giga ati Yunifasiti pelu ati pe ilẹ ti wa fun awọn eto naa. Ẹwẹ, Oloye Ajanaku sọ pe awọn ti ṣetan lati bẹrẹ eto ẹkẹ agba.

Ninu ipade kan ti Egbẹ naa ṣe lai pe yi ni ilu Agbadarigi (Badagry) ni Oloye Ajanaku ti sọrọ naa.

Oloye Ajanaku ẹni ti o han gbangba ninu ọrọ rẹ pe o nfọ esi si ọrọ awọn kan so pe, "Ipade tiwa ki i ṣe lati ba ilu jẹ bi koṣe bi alafia ati ifokanbalẹ yio ṣe wa ni ilu."

Siwaju si i, Oloye Ajanaku so pe, "Awon elesin ajeji ti tumọ esin ajogunba wa si odi nipa pe, won nsọ pe okuta irin tabi nnkan miran ni a nbọ eyi ki i ṣe bẹẹ bi ko ṣe pe, won je ami ti awon alagbara ilẹ wa lo."

Oloye Ajanaku waa tu kẹkẹ oro silẹ pe ,"Fun peẹri a nrai ami walaa ni Moṣalaṣi. Ṣe walaa ko ti won nkirun fun? Bakannaa ni ami agbelebu wa ni Ṣoosi. Ṣe agbelebu ko ni won ngbadura si?

Bi Ẹlẹsin Ibilẹ se npa etutu ti won npa eran bee ni awon elesin ajeji naa npa eran' ko si iyatọ kankan nibẹ rara.

Nigbanaa ni Oloye Ajanaku tamo ọrọ pataki miran, O ni," Bi awon Imale ti nlo oruko awon Anobi lati toro lowo Olorun, ti won si yan Anobi ni alatina won laarin awon ati Ọlọrun ti awon Onigbagbo naa nfi oruko awon Woli gbadura ti won si yan Jesu ni alagbawi fun wọn niwaju Ọlọrun bẹẹ gẹgẹ ni awọn baba nla wa nfi orukọ awọn ti Ọlọrun yọnu si tọrọ nnkan l'ọdọ Ọlọrun. Oun naa ni Ọrunmila ti iṣe agbọrandun wọn niwaju Ọlọrun."

Bakannaa ni Ọba Agbadarigi Alayeluwa Babatunde Akran Mẹnu Toyi Kinui ba awọn eniyan naa sọrọ iyanju lori riṣiriṣi nipa ẹgbẹ wọn naa.

Lẹhin ti wọn kure ni ipade naa ni wọn lọ bẹ Ọba Agbadarigi wọ ni aafin rẹ wọn si bẹ awọn ibi patakipataki wọ ni ilu naa pẹlu ara rẹ ni ibi ti wọn kọ fi duro waasu ẹsin Igbagbọ ni ilẹ Naijiria ati ibi akojọ awọn ẹwọn ti wọn fi nde ẹru l'aye atijọ.



OLOYE FAGBEMI AJANAKU
Araba Eko

## Iyalode jade laye

WỌN ti kede iku Iyalode ilu Eko-Ende ni Igbimọ Ijọba Ibilẹ Ifẹlodun, Oloye Jolaade Abebi.

Irohin so pe, Iyalode naa lo ọpọlọpọ ọdun l'aye ki o to fi ilẹ bora bi aṣọ.

Ọpọ ọmọ ati ọmọọmọ l'o gbehin rẹ Ara won ni Alhaji Tiamiyu Ajiboye Omoiya, Matanmi Ajiboye ati Adebọwale.

Ọpọ eniyan lo wa si bi isinku Oloogbe naa ati ẹlẹgbẹjẹgbẹ.

# Ile Eko Larubawa Omupo ri iranlowo

IJỌBA Orilẹede Saudi Arabia ti tun ṣe iranlọwọ oluko imọ ijinlẹ nipa ẹsun Islam ati ede Larubawa meji fun ileẹkọ Arabic Islami Advaneed School (A I A S) ti o wa ni ilu Omupo ni agbegbe Ijọba Ibilẹ Ifẹlodun ni Ipinlẹ Kwara.

Awọn Olukọ na ti wọn jẹ oluko lati Yunifasiti ilu Medina ni Orilẹ-ede Larubawa ni Falilatu Mola Ibrahimir ati Muhammed Hassani Hamad

Ẹniti o sọ eyi di mimọ fun Onirohin ni, Alhaji Salawudeen, ti iṣe Alakoso ile-ẹkọ Arabic Islamic Advaneed School, Omupo nigbati o ba awọn oniroyin Irohin sọrọ ni pa il siwaju ati idagbasoke ile-ẹkọ na lati igba ti wọn ti da sile ni nnkan bi ọdun mẹẹdogun sẹhin

Alhaji Salawudeen ni laipẹ yi ni awọn olukọ naa yio bẹrẹ iṣẹ ni ilu Omupo nigba ti awọn Ọmọ ile-ẹkọ na ba wọle lehin isinmi ọdun titun. Alakoso so pe iranlọwọ ti Ijọba Saudi Arabia nṣe fun igbega ati ilọsiwaju ile-ẹkọ A. I. A. S. yi tubo mu ajumọṣepo ati irẹpọ fẹsẹ mulẹ laarin Ijọba Saudi Araibia ati Naijiria paapa julọ laarin awọn Musulumi Orilẹ-ede mejeeji.

O rọ Ijọba Saudi lati maṣe dẹkun iru iranlọwọ bayi fun gbogbo ile-ẹkọ ẹsin Islam ati ti ede Larubawa ti o wa ni Orilẹ-ede yi.

# ABA OFIN

(Lati Oju Ewe Kẹta) miran da silẹ (Ayafi bi ofin Iṣelu yi ba sọ bamiran)

(f) Bi o ba jẹ pe iṣiro apapọ iye igba ti ko fi lọ si ipade ijoko larin ọdun kan ju ọgọrun ọjọ lọ laisi ni idi pataki kan.

(g) Bi o ba jẹ pe o kuru ninu ẹgbẹ oloṣelu ti o ti ipasẹ rẹ wolẹ ti o si darapọ mọ ẹgbẹ oloṣelu miran, ki ile Igbimọ Aṣofin bẹẹ to lo saa tirẹ tan.

66-(2) A o gba pe ọmọ Ile Igbimọ Aṣofin kan ko lọ si ipade ijoko, ko si ni idi pataki ti iru ẹni bẹẹ ko fi lọ si ipade ijoko"

Ẹyin onkawe mi nihin ni a o danu duro lori eto yi. O tun di ọsẹ ti o nbọ lagbara Oluwa.

# Egbe Imole Owuro

12,697 Matthew Adedotun, Ọyọ
12,698 Rasheed Oki Ibadan
12,699 Ganiyu Akanjj, Ọkanle-Kw.
12,700 Rafiu Lawal Ijẹbu-Igbo
12,701 Sunday Daramola, Efon Alaye
12,702 Ayinde Lanhun Ibadan
12,703 Olusukanmi Folorunṣo Badia Kw
12,704 Fasasin Amọo Photo, Kisi
12,705 Olusẹgun Salakọ Ibadan
12,706 Abraham Ọdẹṣọla. Ọyọ
12,707 Sundam Samuel, Oyu Aran,
12,708 Alade Tajudeen Ibadan.
12,709 Fọlarin Babatunde, Ibadan
12,710 Rotimi Apọnjolosun Ilesa
12,711 Isumaila Ayọọla Ibadan.
12,712 Kayọde Atilọla Iragbiji
12,713 Wahabi Ogagun, Omupo
12,714 Sunday Ọlatunde, Ipoti-Ekiti
12,715 Ramọn, Akinwumi, Ibadan

(FUN IGBEGA EDE ATI AṢA YORUBA)
DI
**Omo Egbe Imole Owuro**
(Iwe Idi Ọmo Ẹgbẹ)

Oruko rẹ ..........................................

Adirẹsi rẹ..........................................

Ọmọ Ilu ti o jẹ ..........................................

Jawe yi ki o si poosu rẹ si
DOKUN AJADI
(Akowe Ẹgbẹ
P.M.B. 5230) Ibadan.

# Adigunjale gba awon Odo Naijiria n'Imoran atata

ỌKAN ninu awọn enıyan meji ti won yinbọnpa ni Bareke Ṣọja ti nję Letmurk, Mokola Ibadan ni ọjọ Satide ti iṣe ọjọ kẹrinlelogun oṣu kejila ọdun yi, ti gba awọn ọdọ ilẹ Naijiria ni mọran iyebiye

Ki won to yinbọn pa ni olọsa naa, John Edegbor, gba won ni mọra naa o kesi gbogbo ọdọ Naijiria lati kọ bi a ṣẹe ni itẹlọrun pẹlu iwọnba ohunkohun ti won ba ni ki won si yẹra nibi aye jije.

Ọkunrin naa sọ pe, ki iṣe pe oun jebi esin ti won fi kan oun naa ni, bee ni ko si ohun ti oun ko lẹ fi bura lati fi han pe on ko jebi ẹsun yi bee ni oun ko jale ri lati ọjọ ti oun ti daye. John Edegbor wa so bayi: "Ọlọrun ni eleri mi"

Simaju si i okunrin naa kesi awon Olopa ile Naijiria lati maa fi pelepelẹ ṣe iwadi won daadao "nitoripe o daju pe opo eni ti ko jale ni won ti dajo iku fun ti won si ti yinbob pa

Nigbanaa ni John Edegbor kesi Ijoba Naijiria lati wa ona miran ti won yio fi fopinsi iwa. Idigunjale ni ilẹ wa nitoripe yinyinbọn pa Ọlọsa ko le yanju ọrọ naa. John Edegbor sọ pe, ifẹ ti oun ni si Ilẹ Naijiria lo jẹ ki oun sọ eyi

Ẹnikeji ti won yinbon pa lojo na ni Muniru Adedokun ti inagijẹ rẹ nję Nurrdeen ẹni ti won fi ẹsun kan pe o fi ipa gba rẹdio-Silgvano transisor ti ise ti ti Salawu mobolaji Durosọmo ni ori afara odo gẹgẹ nilu Ibadan ninu oṣu kẹrin odun 1975.

Ẹsun ti won fi kan olosa akoko John Edegbor ni pe o fi ipa gbe Naira mejidinladorun ati ẹgba owo meji ti owo rẹ jẹ ogorun Naira mo Arabinrin Christianah Ọlatunde Ogundare lowo ni ibugbe oṣiṣẹ Ijoba-quater 1008 GRA Agodi Ibadan ni ojo kejidinlogun oṣu kẹwa odun 1974.

Irohin fi ye wa pe, nṣe ni awọn ọlọṣa mejeji bu gbagada sẹkun nigba ti wọn ko wọn de Bareke naa ti wọn ri ẹgbẹẹgbẹrun eniyan ti o wa woran, ti wọn si tun nwo gorodoomu ti wọn to jo.

Awọn ọlọṣa mejeji sọ pe awọn ko jẹbi, won ni o si da awon loju pe lori awon Olopa ati eniyan ti o jeri le awon lori ni Olorun yio ti beere ẹjẹ awon.

# 13

## Aso "Wonyosi"

(Woju Ewe Kini)

tẹ ọkunrin kan ati obinrin kan ti o wa ninu mọto naa.

Ninu mọto Danfo kan ni awọn Ọlọpa ba ọti lile tihin.

Bakannaa ni awọn Ọlọpa Eko ti bẹrẹ si i wa Ọga Ṣọja kan ati iyawo rẹ kiri lori taya ati tiibu alupupu ẹlẹgbaajọ Naira (16,000 00) ti wọn ji gbe.

Ninu ọkọ oju omi kan ni wọn sọ pe awọn ole ti ji ẹru naa ko, ṣugbọn nigba ti awọn Ọlọpa nwadi, inu ile ti Ọga ṣọja kan ati iyawo rẹ ngbe ni wọn ba awọn ẹru naa.

A gbọ pe, awọn tọkọtaya naa di awati fun awọn Ọlọpa ni ile naa. Ọwọ wọn tẹ ọkunrin mẹta pẹlu obinrin meji kan. Ṣugbọn awọn Ọtẹlẹmuyẹ nwa tọkọtaya tihin kiri sibẹ.

Awọn Ọlọpa sọ nilu Eko ninu ọsẹ yi pe awọn ti gba ọrọ silẹ lọwọ awọn eniyan ti ọwọ awọn tẹ l'ori gbogbo ọrọ naa.

## Oba fese fee

(Woju Ewe Kini)

A gbọ wipe awọn enia naa tilẹ bọlu oko ti o wa ni agbegbe, wọn si ba, iṣu agbado, ọka-baba ati eree ti iṣe ohun jijẹ jẹ repete.

A gbọ wipe awọn enia ti wọn fi ilu silẹ pẹlu Oloye Ednbẹ to oji lerugba ati mẹwa (250) Awọn wọnyi ni a gbọ wipe wọn ti lọ si ilu bi i Umugidi, Ọpaha ati Okanehe.

Bayi ọwọ awọn ọlọpa ti tẹ awọn enia diẹ ti wọn nfi ọrọ wa wọn lẹnu wo lori iṣẹlẹ na.


## Omo Akin Nap

N3/305 BỌLA INALENDE
IBADAN
HAPPY NEW YEAR AT:-
BLACKPOOL V ORIENT (W.B. D .
MANCITY V ASTON V (S. B. D.)
NOTTS CO V BRISTOLR ( ? )



## Kere o!

EYI ni lati kede fun ẹyin obi ati alagbatọ pe, aaye wa fun ọmọ yin lati kọ ẹkọ ijinlẹ nipa ẹsin Islam ati ede Larubawa ni ile ẹkọ Arabic & Islamic Advanced School Omupo, via Ilọrin.

Ẹ kọwe bere alaye tabi ki ẹ kuku wa si ọdọ Ọga Agba ile-ẹkọ naa


## OPE FUN IBANIKEDUN

AWA ti orukọ wa wa ni isalẹ ikede yi loruko wa ati gbogbo idile ADIGUN ti ile ADEKẸHIN, OKE MASIFA, OGBOMỌṢỌ dupẹ tọkantọkan lọwọ gbogbo ẹyin ti ẹ wa tabi ti ẹ kọwe tabi ti ẹ fi waya ranṣẹ lati ba wa kẹdun fun iku awọn arakunrin ati arabinrin wa:

(1) Ọgbẹni D.L. Adigun
(2) Iyaafin Esther Adedọja Alabi (Arabinrin Adigun)
(3) Iyaafin Adunọla Alade (Arabinrin Adigun)
(4) Iyaafin Adeoti Lana (Arabinrin Adigun)

Awọn eni ti o kagbako ijanba mọto ni Ọyọ nigba ti wọn nkọja lọ si Ibadan lati Ogbomọṣọ ni ọjọ kejilelogun oṣu November 1977 ti a si sinku wọn ni ọjọ kẹrindinlọgbọn oṣu November 1977 ni Ogbomọṣọ.

Iku awọn ara wa yi ba wa lojiji, a si ri i pe gbogbo awọn eniyan l'ọkunrin ati l'obinrin fi ibakẹdun wọn han wa lọna ti o ya wa lẹnu, eyi mu ki o ṣoro fun wa lati maa daruko ẹnikọọkan ninu iwe idupe yi.

Adura wa ni pe, ki Oluwa bukun gbogbo yin.
A tun gbadura pe, ki Oluwa ba wa tọ awọn ara wa si afẹfẹ rere Amin.

Ọgbẹni J. Ọladeji Adigun — Oloye. J. Ọla. Adigun
(Fun Gbogbo Ẹbi)

Printed and published by the People's Star Press Limited, N4/496B Yemetu, Adekile Ibadan. Lagos Office: 18, Odunlami St. Phone 97017. Aladorin P. M. B. 5030, Ibadan. Olootu (Editor) Lawuyi Ogunniran, E4/803, Aperin